# EJO IGA IDUNGANRAN DI RIRO NILU OYINBO




ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO




VOL. No. IX 515 ELETI - OFE LAGOS, SATURDAY, APRIL 13, 1957. KOBO MEJI (2d)

## Ejo Iga Idunganran Di Riro Nilu Gesi

Omoba Adeyinka Oyekan lo gbe ejo lo silu Oyinbo ni waju Oba Gesi wipe, on ko fi ara mo ejo ti nwon da fun on nile ejo Kotemilorun ti nwon se nile Nigeria, on si fe ki nwon wa soro na gegebi ofin ti lo nipa oro ile Iga Idunganran. Nigbati kotu na ba si lehin odun Easter ti o mbo yi ni nwon fi riro ejo na si a si ni ireti wipe ojo merin ni nwon o fi ejo na. Musendika Adele ni omo Oyekan pe lejo.

Eniti yio se agbejoro (Lawyer) fun Adele ni Ogbeni Hartley Shawcross, ti o nse egbon Christ: Shawcross ti o wa se ejo Banki nile yi. Ogbeni yi Hartley Shawcross ti so wipe, on ko ni se ise Loya mo, ise iselu ni on fe lati ma se, sugbon o ti gba lati pada sise Loya nitori ti ejo Adele yi. Loya kan ti o ti wa silu Eko yi, ti nwon npe ni Dingle Foot ni yio se agbejoro fun omo Oyekan.


OBA ADELE II

Oro ti nwon fe se ejo le lori nisisiyi niyi. Omo Oyekan gegebi Olori fun awon omo Dosumu so pe Iga Idunganran je ini ti baba won Dosumu, sugbon Adele gegebi Olori fun awon omoba yoku so pe nse ni nwon fi Iga Idunganran le Dorumu lowo fun titoju.

**THE NATINAL BANK**
**Of Nigeria Limited**

Incorporated in Nigeria in 1933
Paid up Capital - £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria.
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS, NIGERIA
22 Branches throughout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA,
ILARO, BENIN-CITY, WARRI,
SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS.
LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell
Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams: Natbaniger, London.
Head Office Representative in London
Ernest Olubunmi Obasa—Porter
CORRESPONDENTS
NEW YORK PARIS HAMBURG

## Jamba se oko Reluwe ni Teson Agege

AGEGE. Awon alufa so wipe Iku ti o npaa enia ojo kan mbo wa ti iku yio pa Iku ti o npa enia papaa. Bakanna ni a ti ngbo wipe Oko Reluwe se jamba fun enia kan sugbon Ijamba na sele lori oko Reluwe papaa ni Agege.

Lojo Jimo, ojo 5th osu April ni Teson Agege, ni akoko asale ni jamba na sele lori oko Ibadan kan ni buso mejila si Eko meji ninu awon ti o nsise ninu oko na rasu patapata. Eniketa won nigbati nwon ma fi yo o jade ninu arin meji irin gbongongbongon use lo npoka iku Ki awon to le gbe awon oku meji ti a wi lakoko nse ni awon Onibita (Gangers) sise tosan-toru ti awon nko erupe kuro ki nwon to ri won ko jade nibiti o gbe ti sin won laye.

Oruko awon mejeji ti nwon hu jade ninu ile na ni, Fireman ti a npe ni R. Ojo ti o ngbe No. 135, Griffith Street ni Ebute-Meta. Eni keji re ni Ashpan boy ti a npe ni Y. Ake eni keta ti nwon ri gbe jade larin awon irin gbongon-gbongon ni Fereba oko na ti a npe ni Raphael Manafa ti o ngbe No 30, Griffith Street Ebute-Metta o si je omo ilu Aguleri ni agbegbe ile Onitsha, o sese dagba di omo odun metalelogbon ni, oku o fi omo meji sile.

Awon ero iworan ko jeki awon Olopa ri aye sise won, papaa nigbati moto Alarun de lati wa gbe awon oku na, pelu pelu ash panner ti a npe ni Ake, nse ni oko ge si wewe, ki nwon to ri eya ara re pe o fere to agogo kan abo ojo keji, nse ni gbogbo ara re bo borokoto.

Oku ti Ojo Fireman ni nwon koko ri hu jade. Oko ti jamba se yi je ara awon oko ayara-bi-asa ti nwon npe ni River-class Engine ti nwon fi ranse lati ilu Oyinbo lati ko awon eru epa ti o dabi oke nilu Kano wa si idiko ni Apapa.

Akoiti gbo idi pataki nipa sababi ti o mu oko na subu sugbon ohun ti a koko gbo ni wipe, nse ni oko na nko awon wagon oedu lo si Ibadan Nigbati o de Agege, ibe lo gbe ni lati pade oko miran ti o mbo lati ona Ibadan. A gbo wipe ni ena ibiti nwon gbe ni lati gba koja ara won, aye ibe kere jojo, bayi ni oke ti nsare wo ile ba sola eyiti o duro pelu agbara, o di yakata.

Awon alase Reluwe so pe, iru jamba ti o se oko Reluwe yi je jamba (Class "A") nwon si ngbaradi lati se iwadi nipase re ki nwon le mo eniti o jebi ninu won, tabi lati odo eniti asise na ti wa.

## Orire Owo

Awon Yoruba nda a-a kan ti o fere dabi ere omode, sugbon ko nse ere omode bi kose ayajo pataki. Eniti o ba si fe ki o gba a si od d. Tiburuku, ti rere iwe si dan a wo, Awon Oyinbo, ki nwon to pe ohun kan na iro,nwon o koko ... nlan

(Wo yoku loju ewe kejo)

# Agb'aja Ta Fi R'obo

Lasiko kan adie ati Aja jumo nse ore, ore sise won na dun tobe ti awon eiye ati awon eranko ko fi le ridi awon mejeji. Enia bi aparo sa li aiye ife, awon eiye wa nlo se keta fun Orisa pe awon ko fe adie mo larin won. Orisa bere wipe kilode o nfi asiri omo eiye han omo eranko. Nitori na, ni igbati Orisa gbo eyi, o dake kole titori oro esua yi se ohun kan fun adie, sugbon, o ni sinu.

Nigbati o se, adie yin ogun eyin, o si pa ogun na. Orisa binu, o wipe nitoriti on ba adie wi fun iwa aidara ti o hu o titori re, ko pamo daradara Nje lati te Orisa lorun, nigbati adie tun ma saba, o ye ogbon eyin, o tun pa ogbon omo adie.

Agbare gbabo, Orisa gbe adie ta fun enia ni egbaji, o wa fi owo re ra eiye Awo. Nigbati awon eranko gbo pe nwon gbe adie ta fun enia, awon na tun lo se keta Aja wipe awon ko fe mo larin won nitoripe ileya re poju Orisa tun gbe aja ta fun enia o fi owo re ra obo.

Eyi na lo di owe ti nwon pa loni wipe, "Adie ye ogun, o pamo ogun, o ni [illegible] pamo re, o ye ogbon o pamo gbon sibe, o ni ko pamo; o wa gbe adie ta o fi owo ra Awo, nigbati Awo ye mefa, o pa okansoso, ko ha tan bi?

Owe keji ni wipe, nitori pe aja ie loso ni nwon se gbeta ti nwon fi owo ra Obo, Obo dahun wipe ise kini ir an baba nla on nse?

# Omolanke ko gbodo gun ori kereni lasiko wonyi

EKO — Nwon so wipe, awon Olomolanke, a ma se idalowoko fun awon moto lori kereni, kaka ki nwon ya kuro loju ona fun moto ese ni nwon o di omontaku si oju ona, nwon ko si [illegible] ohun [illegible] te e [illegible].

Nitori [illegible] eyi, awon Igbimo Lagos Town Council ti se igbimo po pelu Oyinbo Seriki [illegible], ati Atoni Genar (Attorney General) wipe lasiko ti moto ba nrin pupo, ki nwon mase fun awon Olomolanke laye lati gori kereni.

Iwonyi ni aseko ti a ko gbodo gbe Omolanke gun ori kereni Ni ojo Monday si ojo Friday, lati agogo meje owuro si agogo mesan owuro. Lati agogo mejila a [illegible] osan si agogo meji osan. Lati agogo merin irole si agogo mefa irole.

Sugbon lojo Saturday lati agogo meje owuro si agogo mesan owuro ati lati agogo mejila osan si agogo meji osan.

Nwon tile so pe awon olomolanke nwon nko eru ti o poju agbara won lo nipa be nwon o ma fi se idaduro fun awon elomiran.

# Igi Ganganran Fere Gun Orun Loju Ni Ila Orun

Awon Yoruba lo ma npa owe bayi wipe "Adie nje fun ara won, ko leriwo", beni oro awon igbimo N.C.N.C. ri ni Ila Orun nigbati nwon se igbimo.

Ogbeni ti a npe ni P.N. Okeke, ti o nse asiwaju awon Ibo ti ko nse ara ile Onitsha, ati wipe o je okan ninu awon elesin ijo Aguda, on lo tako Ijoba wipe, ona ti Ijoba Ila Orun ngba fi se ijoba won, ko nse eyiti o besu o rara.

A gbo, won ni o so wipe, awon Minista ti o wa ninu igbimo na, a ma soro kasakasa, ni iru oro ti ko mo iyan lori, oro ti wipe tani ma mu ni, eyi ko nse ohun to dara rara.

Lehin na lo tun so pe, ona ti ijoba Ila-Orun ngba fi se ijoba ko ye ni si, Eastern Information Service ti o je wipe owo ilu ni awon nlo lati fi sise iwe irohin na, ijoba ti so iwe irohin na, di tire, eyiti ko lati jebe rara. Lehin na lo wa mu eon kan eko Olofe ti ijoba gbe lati se ninu odun ti a wa yi, Nse ni awon elesin Aguda ti o wa ninu igbimo na ati awon Aiatako ijoba da muso fun, sugbon nse ni awon elesin yoku se sio re.

Ogbeni Okeke so wipe nile Yoruba, Ijoba Iwo Orun pin owo bi Iwon 40 Percent fun ilewe kokan sugbon ijoba Ila Orun ko fun awon ilewe kan lowo. Gbogbo ilewe ti nwon ba ko ni ehin odun 1957 ni Ila orun, ijoba ko ni fun ni owo iranlowo, ayafi eyi ti Local Authority ba ko.

A gbo wipe gbogbo oro ti Ogbeni Okeke nso yi, ko si eyi ti o wo eti ijoba nibe, kaka ki nwon teti lele ki nwon gbo, nse ni olohun bere si yohun; ti nwon si nso iru oro bayi pe "Figbimo sile". "Lo jo ara re" Bi nwon ti npariwo ki ori okunrin yi le daru tabi ko ma mo ohun ti o nwi suru ni o fi segun na, Lehin to pari oro re tan, ijoba ko si fesi soro re na.


## Polowo Oja Re Sinu Iwe Irohin Eleti - Ofe






## Ogun Aran (Ejo Inu)

Aradan Worm Expeller je ogun aran pataki fun omode ati agba okunrin ati obinrin. Ra igo kan lati ya gbogbo awon aran buburu ti o nba o ja ninu danu. Bi o ti npa aran, beni o npa eyin won. Wa ra tire ki o to tan. Igo kan je 2/6d. Owo-Okó si je 1/-.

THE EGBA TRADING ARADAN STORES,
18, Denton Bridge Street,
P.O. Box 2, Ebute Metta.


No 50

## Vacancy For A Master, King's College, Lagos

Applications are invited for the post of a Master, King's College, Lagos.

Particular in Government Notice No 564 in the Federation of Nigerian Gazette of the 28th of March, 1957.

No. 51

## Inland Waterways Department Sapele / Benin Ferry Service

It is announced for general information that the Sapele / Benin ferry service will shortly be closed for a period of ten days, in order to enable the Public Works Department to effect essential repairs to the road ramps.

It is hoped that a week's notice will be given regarding the actual date of closure.






## Oloye Awolowo Ati Igbimo Re

Oloye Awolọwọ ni a nwo ti o joko larin awọn igbimọ rẹ, o si ti jẹ apa rẹ lati ma bere imọran lọdọ awọn igbimọ rẹ, ki o to d'awọle oha kokua ni yiye.

Nina aworan yi Awolọwọ lo joko ni arin meji ninu awọn igbimọ rẹ ni mba jiroro pọ.

## Nigeria To Get Vital New Drug

At a Press Conference on 2nd April 1957 Mr. J.C. Mottram announced Pfizer, discoverers of Terramycin the 'wonder drug' of the antibiotics, who in February sent supplies to the Health Department in Lagos and the Jericho and Shagamu Hospitals in Ibadan, that a remarkable new drug known as Sigmamycin is soon to be made available in Nigeria.

Mr J.C. Mottram, Pfizer's territorial manager for the African countries, said that the new drug was a striking advance in the treatment of all infections for which antibiotics are used.

"Over a year ago, "said Mr Mottram, "our research staff informed us that the answer to one of medicine's great and growing problems today – the patient's toleration to antibiotic treatment and the emergence of microbial resistant strains – probably lay in the combination of selected antibiotics. They were given priority facilities to press forward with this line of study. They produced the desired result – a multi-dimensional antibiotic. It is a new concept of the principle antibiotic therapy. There is no doubt that the discovery of Sigmamycin marks a most striking advance in the treatment of all the infections for which antibiotics are used. The ideal antibiotic is one that has a wide range of effectiveness, is well tolerated; gives rise to no side effects and to which no organism ever becomes resistant. Sigmamycin is approaching that ideal.




E Ma Ka Iwe Irohin

Eleti-Ofe Fun [illegible] Aladun

Y[illegible]

**ELETI ỌFẸ**

A-NJU-WỌN KO SB WI L'EJQ

EDITORIAL OFFICE & WORKS 28, Kosoko Street, Lagos P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAM "ELETI - QFE LAGOS" Phone 23370

VOL. IX. NO 515. LAGOS, SATURDAY APRIL, 13. 1957

# Ọrọ Buruku Niyi !

Ẹnu kekere kọ l'o ya wa nigbati a ri ikede ijọba Oke-Ọya awọn ọmọ alahusa lori ọrọ ọba Ọlọfa tilu Ọffa ti o sọ wipe ijọba Gambari ko tilẹ ka ọba Yoruba kankan kun bi ọba ni ilẹ wọn, gẹgẹbi ọba fun awọn enia rẹ; ṣugbọn awọn ka awọn ọba Yoruba to wa lara ipinlẹ awọn si gẹgẹbi "Baba Olorişa" tabi aşiwaju awọn enia rẹ nipa ẹsin.

Nwọn tilẹ wa şe gegele le ori gegele, nigbati nwọn tun dagi le lori wipe bi ẹnikan ba şe atako ọrọ yi, oluwa rẹ yio [illegible] nipa lilẹ gba ẹwa l'ọgba onigo pẹlu owo sisan s'apo ijọba. Ede abuku kan ko tun le ga ju iru eyi lọ, nigbati o ba ti le jẹ wipe awọn iran miran ti o ba ti yatọ si iran ti o ni ijọba ni ikawọ ko gbọdọ tun jẹ ogun lẹẹdalẹ ilu rẹ mọ, ayafi ki a gba Wura kuro lọwọ rẹ ki a gbe Anda wura le lọwọ tabi kini ati le mọ iru ikede yi si o, ẹnyin ara ?

Ohun ti gbogbo enia njija du nisisiyi ni ki ohun awọn Ogunna gbomgbo wa mẹtẹta papọ ki a le ri oju eto ilu wa ti a mba lọ silu Oyinbo, ki o ma si wipe a nta ko ara-ẹni lọhun, njẹ iru iwa kobakungbe bayi ni ohun ti o le mu ipapọ wa duro? rara o, ayafi wipe ki afi arawa s'ọtan.

Nitorina, a fi wosika yi kesi awọn enia wa ti yio lọ silu Oyinbo wipo "Ẹşe're ẹ şe're o, Ajiborişa ẹ şe're.

Odi ọwọ yin o,

## Awọn Manager Titun



B. O. DOHERTY



R. ORABUCHE

Ẹniti a nwo aworan rẹ yi ni Ọgbẹni B.O. Doherty ti awọn igbimọ African Timber & Plywood Ltd ti ilu Sapẹlẹ ro si ẹtọ lati fi jẹ olotu işẹ yi. Olotu yi jẹ ọmọ ọdun mẹrinlelọgbọn ilu Zaria lo gbe kọwe de iwe mẹfa, lẹhinna lo tun yege ninu idanwo işiro. O bẹrẹ işẹ lọdun 1940 o nşe Tally Clerk nigbana, ki o to wa di igba keji akọwe ti o nşiro owo. Ni ọdun 1953 lo di ọkan ninu awọn ti o nkọ işẹ Aşọgbo, nigbati o si pari ẹkọ rẹ tan, ni nwọn ro si ẹtọ lati gbe si ipo Olotu (Manager) fun African Timber & Plywood Ltd. ni oşu ibẹrẹ ọdun yi. January 1957.

Ẹniti a nwo aworan rẹ yi ni Ọgbẹni R. Orabuche on ni nwọn tun gbe sipo Olotu, (Manager). O kọwe ni Edo College nilẹ Benin nigbati o yege ninu idanwo senior Cambridge lo ba fi ilewe silẹ, o si bẹrẹ işẹ ni African Timber Plywood & Ltd. gẹgẹbi akọwe kekere ni 1952. Lẹhin na lo di ọkan ninu awọn akẹko Onigbo, o si şişẹ oşu mẹsan ni bi işẹ ẹrọ. Nigbati işẹ si gbe kuro nibẹ, ki o to lọ pade orire ti a si gbe ga sipo olotu (Manager) işẹ yi ninu oşu Jan. 1957.

## Idahun Si Ibere Aboru Aboye OLOTU.

Gegebi ogbeni Aboru Aboye ti so wipe Adele-mo-fori je oruko asije, inu mi dun lati fi ye alagba na wipe,

Wo iyoku loju ewe karun



## Awon to lo ko ise Asagan nilu Oba

Awon enia to duro ti a nwo aworan won yi, ni awon eniti igbimo Marketing & Export yan lati lo ko ise Asa'san nilu Oyinbo, nigbati ikunsinu po lati ilu okere wipe awon koko ti nwon nko wa lati ile Nigeria ko dara to. Awon enia na je marun, okan ninu awon olotu igbimo Marketing & Export lo duro lehin won ti a nwo n.

## Orisa Eyinle

Ninu ogun Elduwe, Eyinle se gudugudu meje fun ogun awon ara Ilobu, on si li eniti o tafa ti o fi pa Balogun Kara ti o wo ewu irin ni iwaju ogun Ilorin, Eyi lo jeki Eyinle di orisa nilu Ilobu titi di oni,

# Arin ajo lati Eko si ilu Port harcourt-

Lati ọwọ Ẹsọ Ikoyi

Dokita lo sọ fun mi pe, o ye ki ngbategun lo silu to jina, yala ki nlọ si Nguru tabi Portharcourt Ọpọlọpọ awọn aririn ajo lo gba mi ni imọran wipe, bi o ba jẹ wipe nitori ti atẹgun ni mo ṣe nfẹ rin irin ajo, ilu Portharcourt ni ki nlọ, nitoripe lasiko yi ni oru ma nmu pupọ ni Nguru. Ati wipe irin ọjọ mẹrin gbako ni ọkọ reluwe yio fi rin irin na.

Afara ko si, mo ti bẹrẹ si palẹ irin ajo na mọ. Mo ra ẹja tutu, mo din, mo se ẹran, ẹja, igbin ati panla papọ, epo ororo ni mo fi se, nitori ki o ma ba sun, mo se iresi, mo ra buredi, mo se iṣu. emi pẹlu iyawo mi ko ẹruo di Iddo.

Iwe Ṣekọn-klasi (2nd class) ni mo gba. Emi ni kan gba odidi yara kan pẹlu iyawo mi. Laifa ọrọ gun, ọkọ ṣi, o f'ori le ọna. Mole goke, mole sọ, Oke t'alajapa ko legun, mo ti gun; m ti sọ, mo ti gun mo si lọ mo ti sọ. bẹni ọkọ basbu ere si.

Lati Iddo si Agege jẹ buso mejila opopo kan ṣoṣo lo jẹ lọtun ati losi ni iwọ yio ma ri ile to dara to si gbadun. Bi ọkọ yi ba ti rin kuṣẹ kuṣẹ ao kọja ni station kan. Ọkọ na duro mu omi ni Itori ati Aro. Wo mi na Awe! ilu Abẹokuta dun wo lokere kedere ni enia yio ma wo Oke Olumọ. Ilu ti a le fi we Abẹokuta ni ilu awọn Aruna kan ti a npe ni Gerti. Nigbati o ku bi buso kan ki a de Ibadan ni a ti nri Oke Mapo. Nigbati a kuro ni Ibadan ilẹ bẹrẹ si ṣu. A fẹrẹ de Kuntaweji ki ilẹ ọjọ keji to mọ.

Nigbati a de Sunguru ibẹ ni awọn nṣe ẹda Irori silẹ meji, meji. Ki a to de ilu yi ni a de eri oda shoyaya kan ti nwọn npe ni Odo Kaduna, gẹgẹbi okun ti nru soke sodo, bẹ gẹgẹ ni odo yi nṣe. Nigbati ọkọ kuro nibẹ, o kori si ilu Minna. Ilu yi ni ekeji ti a le fi we ilu Abeokuta nipa oke apata.

Bi oko ba kuro ni Minna yio ma gba egbe apata gbọro kan koja Bi enia ba gbe awo soju fi wo ara apata na yio ri awọn ejo nlanla ti o wa ye orun lara okuta na. Nigbati ile ojo keji ṣu, a de ilu Kaduna Junction. Nihin ni wahala nla gbe wa fun awọn ti o wọ ọkọ 3rd class, nitoripe, nwọn ni lati pale eru rwon mọ ki nwọn si lọ wọkọ ti o nlo si pata, Awọn towa ninu 2nd class ko ni wahala, ọkọ ni yio wa so wagonu tiwọn.

Lagogo mejila oru, oko wa tun ṣi kuro ni Kaduna ile ọjọ kẹta mọ wa si Kafanchan. Nigbati a de ilu yi ibẹ ni nwọn ti nṣo bọta ta, ati eni Hausa alabara ati abẹbẹ, ohun kan ti o yani lẹnu nilu Kafanchan ni wipe ko si oju agbara nilu na, bi ojo ba rọ, ile ti nwọn ko ba mọ ki o ga soke, nṣo agbara ojo yio ma ya wọ inu ile. Ni agogo mewa ojọ kẹta ọkọ wa ṣi kuro ni Kafanchan pẹlu ere ti o ga, lati ibinyi lọ, ko si gbọ mọ, ayafi papa. Ilu Lafia bi o ti tobi to, ninu papa lo wa.

Nigbati ọkọ ṣi kuro nibinyi a bẹrẹ si nkan ilu awọn Aruna Abitọyẹri, gbogbo ilu wọn jẹ oke, Ọkọ nrin fun odidi wakati mẹrin ti ko ni kan station rara. Ibomiran lọ tobẹ ti o jẹ wipe ibiti ọkọ ti gba kọja ni owurọ, ẹgbẹ rẹ ni ẹkọ yio gba kọja ni irọlẹ, bẹni ọkọ yi nsare buruku-buruku.

Bi ọkọ ba ṣi ni station kan ni agogo meji, iwọ yio ma wo station keji lokere ṣugbọn o di agogo marun abọ ki ọkọ to de ibẹ. Nibomiran, ẹwẹ, bi ọkọ ba nlọ, enia fẹrẹ le bọ silẹ lẹ tọ, ki o tun sare wa mu ọkọ.

Bayi ni ọkọ yio ṣe titi yio fi de odo Benue, bakanna ni Odo Benue ati Ọya ri. Ilẹ ọjọ kẹrin ṣu wa si ilu Makudi ilẹ ọjọ kẹrin mọ wa si ilu Enugu.

AWọn Onihoriho ti Enugu ti nwọn npe ni Wawa yatọ pupọ si awọn Onihoriho Ṣoṣo ti ilu Kafanchan. Nigẹrẹ ti a kuro ni Enugu, nṣ a ti nṣo akiyesi pe, a ṣo nkan ilu ọlaju lati ilu Ovim. Ni irọlẹ ọjọ kẹrin ni a gunlẹ si ilu Portharcourt.

Ohun ti a ṣo akiyesi ninu irin ajo wa yi ni wipe ninu ilẹ ti o wa ni agbegbe Ila-Orun, ti a nebọ orukọ awọn abule lo pọju, Lọsa oju irin Reluwe, ilu Enugu Makurdi, Aba, Omuahia ati Portharcourt lo jẹ ilu ti o fara mọrr pọ. Gbogbo irin ajo mi lati Eko si ilu Pọta jẹ irin ọjọ mẹrin fun Reluwe ti o nsare ẹsan-toru, o si jẹ adọfa-lelẹgbẹrun bus, (1,110 miles)

## Olaleye Somoye



Ọmọde ti a nwo yi n' Ọlalẹyẹ Ṣomoye, ọkan ninu awọn ọmọ oṣiṣẹ U A C. ẹniti awọn oyinbo Onişowo U.A.C fun ni Ẹkọ ọfẹ lati lati lọ kọ ẹkọ ninu ilewe giga, Grammar School Ibadan

Ọmọ-ọdun mẹrinla ni ọmọ na, Ilewe ti o kọkọ bẹrẹ si kọ'we ni Methodist Mordern School Ibadan o si jẹ ọmọ bibi inu Ogbẹni W.O. Ṣomoye, ẹniti o bẹrẹ iṣẹ lọdọ U.A.C. ninu ọdun 1941.

## IDAHUN SI IBERE ABỌRU ABOYE

Obẹrẹ loju ewe kẹrin

oruko na ko nse asije rara Gegebi awon Alagbara aiye igbani ti nje Adele-mo-fogun loto. Eyen ni wipe Alagbara na ni yara ile kan ni bi ti o nko awon egbogi re pamo si.

Atele-igi-jogun. Iyen ni pe alagbara na mo orisirisi ogun ti nwon ba ti ri igi kan, nwon mo iru igi ti nwon le dapo mo ki o to di ogun. Bayi ni orisirisi awon oruko na ni itumo tire lototo.

Nitorina itumo Adele-mo-fori loto ni eniti o nda fila yala fun tita tabi lilo.

Emi ni
E. A. Adekeya
ara Eko.

# Igbimo Onikoko ile Ghana mbo wa be Nigeria wo



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni awọn Igbimọ Onikoko ti agbegbe Iwọ Orun ilẹ Nigeria lasiko ti awọn lọ be ilẹ Ghana wo.

Nigbati o ba di inu oṣu July, a gbo pe awọn Igbimọ Onikoko ti ilẹ Ghana yio tun wa be agbegbe Iwọ Orun ilẹ Nigeria wo fun ibẹwo ọjọ mẹfa pere,

# Ami Ara Ati Itumo Re

a. Orisirisi ni awon ami ara enia, ati wipe bi ami na ba ti tobi pupo si, beni ire tabi ibi na yio po pupo to. Bi ami na ba yi roboto gege bi bolu, eyi je ami pe rere ni nkan to mbe wa, gbogbo na yio jasi. Bi ami na ba yo si igun, rere ti yio kan oluwa re ko ni pe rara. Bi ami na ba ti dudu pupo to, beni rere tabi ibi re yio pe to. Iru ami be ti o ba bu irun loju ko dara rara, sugbon bi irun oju re ko ba po, eyi dara.

b. Eniti ami dudu yi ba wa legbe ori re lapa otun, oluwa re yio ni owo ati dukia laiye, yio si ni ola pelu iyi lojo aiye re.

d Eniti ami yi ba wa lara ipenpeju re otun yio tete ni oko tabi aya, siwaju awon elegbe re.

e Eniti ami yi ba wa nibi koro oju re lotun tabi losi, je eniti iwa re le, tabi onibinu pupo, bi oluwa re ko ba fi iru iwa be sile, iku ojiji nigbehin re. Iwa pele.

e. Eniti ami yi ba mbe ni ereke otun tabi osi, bo ti wu ki o se wahala to laiye, ko ni lowo, tabi ki o ko ere lo. Sugbo nko ni rago tabi ki o talaka, ebi ko si ni pa.

Eniti ami yi ba wa lara
f. imu re yio je Olorire, lairotele, nitori oluwa re yio ti ro ara re pin.

g Eniti ami yi ba wa ni gbon re, yio lowo, ola ati dukia lojo, igbesi aiye re yio si ladun.

gb Eniti ami yi ba wa lona ofun re, yio je ogun owo lati odo oko tabi iyawo re, sugbon ki o soro nibi wobia ati ajeki.

h Eniti ami yi ba wa lara igbaiya otun re, yio si ipQnju die nipa aisan yio si ma bi omokunrin pupo fun obinrin lo, sugbon bi o ba se lara igbaiya osi lo wa, oluwa re yio ma ri ise to lagbara se nigbagbogbo omo re yio si ma je obinrin.

i. Eniti ami yi ba wa ni aria meji igbaiya re, ko ni lowo pupo, beni ko si ni tosi, yio ni alafia, sugbon yio ma ni aisan kekeke.

j. Okunrin to ba ni ami yi nisale omu nibiti o gbe ga die ju okan lo, yio ni ife gbigbona, sugbon iwa re ko ni jeti omoluwabi. Bi o ba ie pe obinrin lo ni iru ami bayi, yio ni ife toto si gbogbo enia ati oko re.

k. Eniti ami yi ba wa ni egbe otun re, yio je eniti oro ko ntete ye, ayafi bi a ba se asotunso fun.

l Eniti o ba ni ami yi nigbaroko otun tabi osi, yio bi omo pupo, lokunrin ati lobinrin.

m Eniti ami yi ba wa lara itan re otun, oluwa re yio ni owo nigbati obinrin ba wa lode re yio si kuse bi obinrin ba ko sile. Sugbon eniti tire ba wa ni itan osi gbogbo awon ti iba sanu fun ni yio so di ota re ko ni lore kan, ayafi ota ni yio ma wa funra re yio si talaka, bi enikan ba nsoro yio ropo on ni nwon nbu, yio si ma wa fura si gbogbo enia.

n eniti ami yi ba wa ni orunkun re yio fe oko tabi aya ti nwon ko ni fi ara won sile lailai, sugbon bi o ba ni orunkun osi, oluwa re, yio je enia rere sugbon awon lo ma pe ni enia buruku

# Mayor Binu Jade Kuro Ni Igbimo

ENUGU. Rudurudu, ati jagba-jagba ni awon igbimo Enugu Town Council fi tuka, nigbati oro se bi oro, ti o di ohun ti odidi Mayor ilu fi ni lati binu fi igbimo sile. Awon enia mejila lo binu jade kuro ninu igbimo lati fi se atilehin fun Mayor. Ki o to di wipe Mayor yi binu jade, o se pe, igbimo ti oni yi ke dara nitorina, on ye igbimo na si ojo miran.

Nigbati igbimo tun pade lati yan awon oloye si igbimo na, enikan damoran pe, ki nwon ye ojo ipade na si ojo 10th osu April, nigbati Sardauna Sokoto ba pada dele. Njhin ni igbimo wa di olohun-ro-ohun. Pelu bi igbimo na ti daru, enikan so wipe, o daru, ko daru, ki nwon ma ba igbimo nlo.

Oro yi ti de eti awon obinrin oja, olukuluku won fa gele ati oja won leti, awon kori sile igbimo wipe, ko mo niseju awon ni igbimo yio yo Mayor ti o nse olore won kuro loye, nwon gbe asia won dani Egbe Alata, Egbe eleja Egbe Aladie ati bebe.

Awon obinrin npariwo wipe, nkan ti o ba se ti nwon ko fi yan olori awon ni Mayor, ayafi bi nwon ba da igbimo na ru, ki nwon tun yan omiran. Bakanna ni awon Hausa tun gbejikan wipe nwon ko gbodo yo ara ilu won kuro ni Mayor.

# OWE YORUBA

Adie ye ogun, o pa ogun e ni adie ko pamo re, adie tun ye ogbon, o pa ogbon, e ni adie ko pamo re, e gbe adie ta, e fi wo ra awo, nigbati awe ye meje, o wa pa okansoso, Abo re o


Vespa Motor Scooter
Must be WON

Lucky numbers with each of our exclusively designed Brooches for GHANA and NIGERIA 3/6 each from our Agents through-out West Africa or direct from
Buyers' Agents Ltd.,
Andover,
Hants,
ENGLAND.



IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Enyin abiyamo ewa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

OMORELA BABY MIXTURE
(SILE MEJI ABO 'ISA, FUN IGO KAN)

O wa lodo —

COMMERCIL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)
10, VICTORIA STREET, LAGOS

Nje ise agbara ti o se l'oko ni? Fi egbogi yi pa ibiti o ndun o.



## Adajo se Ikilo fun awon sere-kóde Eko

Obinrin gbajugbaja kan lo ba odidi awon enia merin jijakadi ti erjwo nse ge, tobe ti awon olopa fi ni lati dasi fun won, nigbati nwon ko ti nwon ko gba, ni o ba ko won lo si kotu.

Awon oniis nwonyi se orire tobe, nitori o ti di asa fun awon obinrin Eko, bi o ti wu ki nwon gbajumo to, tabi ki nwon lola to, tabi ki nwon tile mura daradara bi omo Olo ni to, bi ija ba de, nwon ko ko lati ba gbogbo oso ara won je tabi ki nwon bana ohun oso baiye-biye ti o mbe lara won. Eyi ni adajo na lero lati fi ko won logbon bi nwon ba jebi.

Sugbon kaba-kaba ni awon alatako won nse tobe ti inu fi bi adajo tofi ni lati da ejo na ru. O si ni ki nwon ma lo. Ki nwon to lo, adajo na se ik lo bayi fun won pe.

E wa, enyin obinrin nwonyi, o to o si ye ki e mo wipe ija ko dola, ko nse iru enia bi e yin bawonyi lo tun ni lati mala nitori ipo owo ai e wa yi, e ko si ni fun awon enia laye lati bowo fun ayin. Gbogbo won si dahun pe, a dupe sa!

**Kere o!**

A ti ni orisirisi ogun Germany to sese de, fun oniruru aisan tokuntin lobinrin. Tete wa ra tire k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES

7, Breroa Road, Lagos

## Olotu Ile onje Lu omo Ilewe

Omo ilewe kan ni nwon ran nise lati lo ra buredi wa, nigbati o nPada bo wa, o pade ore re kan n waju ile onje, awon mejeji si jijo duro nwon nsoro. Ayafi nigbati Olotu ile onje na jade wa ti o ki on mole nitoripe o n pariwo lo ba de on lowo lese o si fi lulu pa on lori.

Nigbati olopa de, olotu ile onje na so wipe nse ni omo na wa jale ki on to de mole nitoripe ki o ma ba salo ki olopa to de.

Adajo pe Dokita ti o ti se itoju omo na lati wa jeri nipa ohun ti o ri. Dokita na si dahun wipe, iba nkan ti on ri ni apa oju okun ti nwon fi dee. Adajo ro oro na siwa sehin, o si pe Olotu ile onje lo jebi, o ni ki o lo san adota paun, bi beko ki o lo si ewon osu mefa.

## Iyafin Agbabiaka



Obinrin ti a nwo ti o ro dede, ti o gba dede ninu aworan yi ni Iyafin Agbabiaka, eniti o wa lo o ose re ni Lord Lloyd ti o fi nhan Iyafin na gegebi nwon ti oro irin. Eyi sele nibi Afihan ti nwon se ninu ... ni London, ti iyawo Ogbeni Agbabiaka, Oga agba awon Olopa ile wa nihin lo sibi Afihan na.

## Awon to lo kose Olopa



Awon ti a nwo ninu aworan yi ni awon enia dudu ile wa, ti nwon lo kose olopa nilu Oyinbo, ti nwon si yege ninu idanwo na. Nigbati nwon kose pari, ti nwon nfe lo sile, ni nwon pe apeje fun won lati fi dagbere po e digba o se.

Awon ti o duro nwonyi lati apa otun J. R Ezeadwingu, S. Ojeme, Dickson B. Kodjoe ati Tom Barratt.

## Oko Ọba Ilu Oyinbo



Ẹniti, a nwo aworan rẹ yi ni Duke of Edinburgh ti o nṣe ọkọ ọba ilu Gẹsi, on lo tẹle iyawo rẹ lẹhin wa sile Nigeria nijọsi. Nigẹrẹ ti nwọn pada de ilu Oyinbo, lo tun bẹrẹ irin ajo miran lọ silu Gambia, nibiti agbọ wipe o yinbon, fun akọ Ọni kan ninu odo ilu na. Bi o ti npada ti Gambia de lo tun kori si ọna ilu Melborne nilẹ Australia, nibiti o gbe lọ ṣi de ere Olympic fun awọn Oṣere Nigbati o pada de lati ilẹ Australia, on pẹlu iyawo rẹ tun lọ bẹ ilu Norway wo ninu ọkọ kan ti nwọn npe ni Britania. Lẹhin ti nwọn pada de lati Norway, awọn mejeji simi fun gba diẹ, ki nwọn to tun bẹrẹ irin ajo ilẹ Faranse nisisiyi.






No. 52.

## Federal Education Department:

VACANCY FOR AN EDUCATION OFFICER

Applications are invited for the post of an Education Officer, Federal Education Department.

Particulars in Government Notice No. 612, in the Federation of Nigeria Gazette of the 4th of April, 1957.

### ORIRE OWO

(O bẹrẹ loju ewe kini)

na wo, ki nwọn to mọ iru suna ti nwọn o pe nkan na.

(a) Bi o ba nlọ si ode lati lọ gba owo ki o wi bayi nigba mẹta wipe Ogẹde Ngba'gbọn G'agbọn Bi o ba le sọ bẹ nigba mẹta ti ko si kọ ọ lẹnu, tabi ki o ṣi pe, mọ daju pe wa ri nkan na gba.

(b) Ṣugbọn bi o ba da ẹṣẹ kan ti iwọ ko fẹ ki a ba ọ wi ki o sọ bayi nigba mẹta Akaba K'a-kaba Ko J'akaba Baba Mi Lọ.

### Ẹ TUMỌ ẸNỌ YI FUN WA

Awọn ara Eko ti o mbẹ ninu awọ Gẹlẹdẹ, nigbati nwọn ba fẹ sọrọ kan ti nwọn ko fẹ ki awọn ọgbẹri ko gbọ nwọn o ma sọ ede kan ti a npe ni Ẹnọ. Ede na si fẹrẹ kari aiye nisisiyi, ọpọlọpọ enia lo le sọ ọ, nwọn si le tumọ rẹ pẹlu. Ede na niyi, ẹniti o ba mọ ọ ki o tumọ rẹ fun wa.

(a) Ọgọpaga agagbegelegekanga tigi ẹgẹhingi logojungu,

(b) Ẹgenigi tegerenge, egejigi tegerenge nigi ọgọjaga figi ngikungu.

Emi ni Ẹlẹnamejì
c/o Eleti Ọfẹ Office
28, Kọsọkọ St. Lagos

## Ọba Obinrin



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ti o de ade sori ni ọba obinrin Elizabeth keji ti ilu Oyinbo, ẹniti o mbẹ lori irin ajo kakiri ilẹ Faranse pẹlu ọkọ rẹ nisisiyi Duke of Edingburgh.

Ki Ọlọrun da ọba si.

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company. 28, Kosoko Street P. Box O. 467 Lagos Phone 23570